CHIEF SECRETARY'S OFFICE
16 OCT 1922
LAGOS

# EKO AKETE.

IWE IROHIN OSOSE.

VOL: I. No. 14. SATURDAY, OCTOBER 14, 1922. THREEPENCE.

*Editor:*—ADEOYE DENIGA,
*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|
| Ọdun kan 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣe si *Editor*

## GBOHUN-GBOHUN.

### ARO PURỌ KO T' ỌDỌFIN.

Ọmọ ana mọ pe ki iṣe gbara ti KINNIUN ONIBUDO (Ọgbẹni HERBERT MACAULAY) de Ilu Oyinbo ninu oṣu *May*, ti ọdun *1920*, l' o ki Iwe rẹ *Justitia Fiat* mọlẹ ni kikọ, gẹgẹ bi Iwe-Irohin *African Messenger* ti sọ ni ọsẹ t' o kọja: ohun ti Oniwe-Irohin yi nsọ ni pe ohun ti Ọgbẹni na kọ si iwe ti a wi yi l' o mu nkan ri bi o ti ri ni ilu nisisiyi. Eyi ki i ṣe otitọ; ohun t' o ṣẹlẹ ni ọrọ ti Ọgbẹni HERBERT MACAULAY ba ikan ninu awọn Aṣoju Iwe-Irohin ti a npe ni *Daily Mail* ni Ilu-Ọba sọ nipasẹ ti ELEKO ati Idile ỌBA DOSUNMU, ni IGA IDUNGANRAN: ninu ọdun *1920* ni eyi ṣẹlẹ: Ọgbẹni MACAULAY ko kọ Iwe rẹ *Justitia Fiat* ti a nsọrọ rẹ yi titi di oṣu *January*, ọdun *1921*, ni *London*, iwe na jẹ esi si Akanṣe Iwe-Irohin Ijọba (*Nigeria Gazette. Extraordinary*,) ti o jade ni ogunjọ oṣu *December*, ọdun *1920*, nipasẹ ọran ELEKO. Iwe na de si ilẹ yi fun tita ninu oṣu *March* tabi *April*, ọdun *1921*, nigbayi ni a ṣẹṣẹ bi Iwe-Irohin *African Messenger*: ṣugbọn ni ọdun *1920*, t' o ngbidanwo ati pitan rẹ yi, o ṣi nrọ 'jo l' ọrun ni!!

### KC SI AỊAMỌLA T' O NI T' ON KO YI.

K' a ma lọ ibosi pe nkan t' emi nikan l' o dara ju ti gbogbo enia ni ilu lọ ki nṣe nkan ti oju-kori-ri. Ni ilẹ yi ati ni gbogbo ilu oke, titi o fi de KADUNA, ni Iwe-Irohin wa yi EKO-AKETE jẹ IGBADUN fun ogunlọgọ awọn t' o nka a: ọpọlọpọ Iwe-Iṣiri (*Letters of Appreciation*) ni a ti ri gba lati ọdọ awọn ọrẹ wa kakiri, t' o jẹri si

Adeoye Deniga — Editor
Akinkoyabirin

Ede Yoruba t' o jire ti a fi nkọ ọ; eyi fihan pe awọn ọrẹ wa wọnyi mọ Iyi Wura t' o wa ninu Iwe-Irohin na. A kole ṣẹṣẹ na 'wọ k' a to f' oru han!!! (Owe ni o.) Ti a ba ni mọ ọ, Ọmọran a mọ ọ.

## ARUN L' ỌTA, ARUN L' ODI!

A ṣe Ipade Ilu kan ni *Monday* ọsẹ yi' ni Ile-Iranti Afari-Ogun, lati da ọrọ Ọsẹ-Ilera rò, nipa eyiti a o ma a ya ọsẹ kan sọtọ l' ọdọdun lati ma a sọrọ Ilera-enia jake-jado ilu wa: Alakoso Ipade na ni Bãlẹ Ilu, (Ọgbẹni Henry Carr) awọn Isangbe rẹ ni Dr. Akiwande Savage, Ọlọla Dr. Ọbasa, Dr. O. Ṣapara, Dr. Clarke ati oyinbo ẹgbẹ rẹ kan. Awọn Ogbufọ ni Ọgbẹni C. B. Olumuyiwa ati Ọgbẹni J. J. Tubi. Diẹ ninu awọn t' o sọrọ si ohun pataki yi ninu awọn ti a fi iwe pe ti nwọn joko sisalẹ ni Ọbanikoro Oloye, Oluwa Oloye, Alufa-Nla J. G. Campbell ati Ọgbẹni Kasumu Ayorinde. Gbogbo Ajọ l' o fi ohun ṣọkan pe ṣiṣe ni ọrọ na, a si yan ijọ karun oṣu *November* t' o nbọ fun ibẹrẹ iṣẹ na, ti gbogbo nkan ba ti yọri k' o toto igbana.

## A KI I RI OKUNRUN ẸIYẸ L' ORI ITẸ. PIRI NI ẸIYẸ OLONGO NJI.

A gbọ pe o fẹ diẹ si Lemomu Brimah ni ijọ melo sẹhin, tobẹ ti ko fi le lọ si Jimo ọsẹ t' o kọja, ṣugbọn Naibi ni Ebute Awo dipo rẹ ni Mosalasi Nla. K' Oluwa ṣe e ni fifuyẹ.

## ABIỌDUN ỌMỌ AJALỌRUN.

A ba ọrẹ wa Ọgbẹni Henry Sylvanus Abiodun Thomas, Igbakeji Akọwe-Agba, ti Ibi-Iṣẹ Ijẹri Iwe Owo Ijọba, (Ebute Mẹta,) yọ fun Oye Baba Ẹgbe awọn Oniṣe-Ọba ti ilẹ yi ati Igberiko rẹ, ti a fi jẹ ni iwọn ọjọ diẹ sẹhin. Oye yi a mọ ọ ' ori. !!!

## ẸHIN KETE L' ỌFỌ NṢẸ.

O bọ si eti igbọ wa pe awọn Ijọ Lemomu ko l' ọwọ ninu rogbodiyan t' o wa lãrin Ijọ awọn Janma ati Ijọ *Ahamadia* nisisiyi; eyi dabi enipe ona Ijọ awọn Imale t' o wa lãrin wa nisisiyi yi pin si ọna mẹrin. Ekini Ijọ Janma. Ekeji, Ijọ Lemomu. Ẹkẹta, Ijọ Alalukurani. Ẹkẹrin, Ijọ Ahamadia.

## IGBẸ L' OWO WA. EKURỌ

Bi awọn oyinbo Ile-Owo wọnyi ti gba Ekurọ l' ọsẹ yi ni eyi:—

| | | |
|---|---|---|
| African & Eastern Trading Corporation (Ẹgbe Idapọ-owo) | ... | £10 10 titi de £11 |
| Ẹgbẹ-Odo-Ọya (Niger Co.) | ... | £10 10 |
| Ẹgbẹ "Bọ-nju" (French) | ... | £10 10 |
| Ile Russel | ... | £10 10 |

EPO

| | | |
|---|---|---|
| Ẹgbẹ Idapọ Owo | £19 10 titi de £21 | |
| Ẹgbẹ Odo-Ọya | ... | Bakanna |
| Ile "Bọ-nju", | ... | £10 10 |
| Ile Russell | ... | Bakanna |

COCOA

Gbogbo awọn Ile-owo wọnyi ngba *Cocoa* ni £24 de £25 fun *ton* kan t' o ba ti jọ jusi.

## WO IBI!

A o tẹ Irohin Jubilee Alake ti Ọrẹ wa Ọgbẹni E. A. Oluyẹle-Bright kọ, lọsẹ to nbọ.
[Ed. E. A.]

Ni iranti Alice ẹniti Õrun rẹ wọ nigbati iṣe Ọsan ni ọjọ *12th October, 1915*.
"Olufẹ ma sun ko si ma simi
Gb' ori le Olugbala rẹ
Mo fẹ ọ :—Ṣugbọn Jesu fẹ ọ ju
Sun-re! Sun-re!! Sun-re!!!—A.

## IPO AWỌN ỌMỌDE.

Eko,
*14th October 1922.*

LETTER NO. 12.

Ẹnyin Ọrẹ mi Ọwọn,

Akoko yi jẹ akoko ti awọn Olukọ ima gbe awọn ọmọ ti o ba ṣe dada ninu iwe wọn larin ọdun kan si iwe titun gẹgẹ bi ẹnyin papa ti nọ, lai ni tabi-tabi ọpọlọpọ ninu nyin ti bọ sinu iwe titun, awọn ẹlomiran si wa ninu nyin ti ko bọ inu iwe titun; fun awọn ti o bọ si iwe titun, mo ba ọn yọ, ṣugbọn fun awọn ti ko bọ sinu iwe titun, mo a wọn kẹdun, mo si gba wọn ni iyanju ki nwọn ...ra lọdun to mbọ, nitori akoko ko duro de ẹnikan "*Time and tide wait for no man*", "Ilẹ nmọ ilẹ ... ọlọjọ nka a".

...Mo ngbero lati ba nyin sọrọ lori Iwa-Imẹlẹ tabi ... ọlẹ eyiti oynibo npe ni *Laziness* lọsẹ to mbọ. Ẹ o ṣe iranti pe mo ba nyin sọrọ nipa otitọ-sisọ ...sẹ to kọja, loni mo fẹ ki otitọ ọrọ na ki o wọ ...yin lọkan lọ, mo fẹ lati sọ itan kan fun nyin.

Nigbati Ọba *Persia* kan ti orukọ rẹ njẹ *Darius* ...sori oye, o se onjẹ fun gbogbo awọn ilu ti o wa ...ẹ rẹ, nigbati nwọn jẹun tan, Ọba lọ sun, o fẹrẹ ...ti sun ni awọn ọdọmọkunrin mẹta njiyan larin awọn pe "Kini ohun ti o lagbara julọ l'aiye". ...tini dahun, o ni, "Ọti (*Wine*) lo lagbara julọ, ...bi o ma nsọ enia nla di aṣiwere, Ọba ati ọmọde ni o ...kanna niwaju rẹ; o ma nsọ enia ti o yẹ ko pe ... ti alaironu. O ma nsọ otọṣi enia di olowo ...wa aṣẹra rẹ. "O ni bi Ọti ba le ṣe nkan wọnyi, o di pe ... o tun lagbara ju u lọ laiye?"

...i dahun, o ni "Ọba alaṣẹ ekeji oriṣa li o julọ." o ni, "Ọba li o lagbara ju gbogbo ... o wa laiye lọ." O ni, bi "Ọba ba ni ... enia ki o lọ si ogun, nwọn ni lati lọ. ... o ba ni ki nwon lọ nwọn ni lati lọ ... O ni, bi awọn agbẹ ba roko tan ... ti nwọn ba ri nibẹ nwọn ni lati mu ... fun u." O ni, enia lasan kan ni Ọba, bi o ... ni ki nwọn lọ pa enia kan nwọn ni lati lọ... a. Bi o ba paṣẹ pe ki nwọn ko da enia k... oluwa rẹ bọ. Ohun rẹ ni gbogbo enia m... bọ, bi o ba ti wun u ni o ma nṣe." O ni, e... ko ha fi han pe Ọba li o lagbara julọ laiy...

Ẹkẹta ...lahun, o ni, Iwọ Ọba, otitọ ni o tobi julọ, ...si lagbara ju gbogbo nkan lọ. O ni, ọti nṣe ...uba, Ọba si buru jọjọ, gbogbo ọmọ enia lo bu... gbogbo wọn ni o si ma ku. O ni, "ṣugbọn ...titọ yio wa titi lai ati lai. Otitọ lagbara nigb... igba, on ko nku, ko si ohun ti o le bori rẹ. Otitọ ki iṣe oju-isaju ẹnikẹni, ko si ohun ti le pa lẹnu mọ. Idi ododo li otitọ ma nwa. On ni agbara, ati ijọba ati ipa ati ọla awọn ar... igba lailai.

Ibukun ni fun Ọlọrun otitọ.

Gbogbo wọn ni ki awọn onidajọ ati Ọba ki o sọ ẹniti ọrọ rẹ dara. Gbogbo awọn enia si ke lohun rara pe "otitọ ni ọrọ ẹnikẹta nitori "otitọ lagbara, o si ju gbogbo ohun ti o wa l'aye lọ. Ọba si dahun o ni "Bere ohunkohun lọwọ mi, emi yio fi i fun ọ, nitori iwọ ni o jẹ ọlọgbọn ninu gbogbo ẹnyin mẹtẹta. Ọdọmọkunrin na si dahun o ni, "Ọba mo fẹ ki o ma wa ni idi otitọ, ki o si mu ileri ti o ṣe niwaju Ọlọrun ṣẹ. Nigbana ni Ọba fi ẹnu ko o li ẹnu. Inu rẹ si dun si Ọdọmọkunrin yi.

Ẹ ma gbagbe itan yi.

Emi ọrẹ Ọmọde,
ELETI ỌFẸ.

---

## AN OPEN LETTER No. I.

### TO THE INSPECTOR-GENERAL OF POLICE.

Sir,

Disquieting news reach me recently, with regard to the prevalent burglarious practices noticeable in town presently, as coming from night depredators: it has been brought to my notice that some Shop-keepers have been the victims of these "Dare-Devils" in spite of the very vigilant and commendable services your men "on the beat" have been, and are still putting forth; yet, it is feared, the position is rendered more intolerable and acute during last few weeks.

Regard it not, Sir, an impertinence on my part, in addressing you in a public journal such as this; but in the light of what has happened as stated above, the community cannot but look up to you, SIRE, as their FATHER who has NOT been leaving any stone unturned in protecting their life and limb, and they trust you will also see to it, that a stronger measure is adopted in running these unwelcomed nocturnal visitors to earth. *Salus Populi Suprema est lex.*

EKO AKETE.

## EKO AKETE.

EKO, SATURDAY OCTOBER, 14, 1922.

### KI LO TO ALAFIA?

Ipade ilu ti a ṣe ni *Monday* ọsẹ yi, ti a rohin rẹ si apakan Iwe-irohin yi, jẹ ohun to wọ pupọ nitori ọrọ ILERA 'ti a tẹnumọ nibẹ,' pe a o bẹrẹ si ya ọsẹ kan sọtọ lọdọdun fun ati ma kede ọran yi: kọ si ẹniti ko mọ pe kosi ohun to yara sọ enia di "Okẹgẹ" ju arun lọ; oriṣiriṣi rẹ ni a si nri ni ilu nisisiyi. Gẹgẹbi ọrọ ti ỌBANIKORO OLOYE sọ ninu Ipade na: OLOYE yi sọ oju abẹ ni 'ko nigbati o fihan gbogbo enia t' o wa si Ipade yi pe ko yẹ ki a fi ẹtẹ silẹ ki a ma a pa lapalapa, eyini ni pe ki awọn Olotu ọran yi sa ipa lọpọlọpọ lati mu awọn abirun bi awọn Adẹtẹ, Arọ, ati awọn ogunlọgọ afọju ti nwọn ti ilu Hausa wa si ilẹ yi, ti nwọn si nba awọn enia abarapa fidi-kodi ni igboro, pada lọ si ibiti nwọn gbe ti wa: a ko wipe ki a ma ṣãnu awọn akuṣẹ: ṣugbọn ẹnikẹni ninu wa l' o mọ ọwọ ti awọn Hausa wọnyi nfi arun ṣe larin wa nibi; pupọ ninu wọn l' o ni mãlu tita ni Songo l' Ebute Mẹta, ti nwọn si ma nmu owo ti nwọn bari l' ọna bayi gba ọna miran, ti nwọn o si ma a doti awọn ara-ilu nipa "bi-baara" t'ọṣan-t'oru ti nwọn ki njẹ ki enia simi, ti nwọn o si ma a jẹ ajẹgba bi ti konkọ!!! a tanmọ pe inu Ilu yio dun lọpọlọpọ ti awọn Alaṣẹ Iṣẹ yi ba le mu iwa yi kuro, yio si jẹ ohun pataki kan ti awọn enia yio ṣ' ọpẹ fun.

A ko ro pe awọn ilu miran ti ko to EKO lọwọ-lẹsẹ ninu okiki, ngba irufẹ awọn ajẹji enia bayi laye lãrin wọn. Laisi ani-ani, a ko ṣi sọ ti a ba wipe awọn enia bayi ti sọ Ilu EKO di Atitan ti Oniruru Alarun le ma a gbe. Niwọn igbati awọn Alaṣẹ Ilu ko ba pa ero pọ lati din jamba yi ku, ewu nla ṣi nbẹ sibẹ.

Ewẹ, fi-fun Ilu nisisiyi tun jẹ ohun idina kan t' o nmu aisan wa: awọn Ilu tọka eyi fun GOMINA ninu Iwe-Iyẹsi wọn si i ni oṣu *December* 8, 1920: a si ni ireti pe eyi ki yio fo awọn BOAINNI t' o wa l' ẹnu ỌSE-ILERA yi da. Nipa aimọ 'ye orile-ede ati ede ti nbẹ lãrin wa nisisiyi, EKO ti di Ilu "Iruwa-Ogiriwa!" eyiyi fi ara han lati igbati a ti da awọn Kuẹ-kuẹ pọ mọ wa nibi, lati ọdun kẹrindilogun ọhun—*1906* ni akoko "AMAGA" ni sã EGERTON, GOMINA wa nigbana, laisọ ti oniruru arun ti koṣe e kọ si inu Iwe-Irohin irufẹ eyi, ti pupọ ninu awọn ajeji obinrin wọnyi mu wọ ilu tobẹ t' o fi jẹ pe ni akoko kan nṣe ni gbogbo nwọn Alaṣẹ Ọlọpa ṣi gan-ngan si wọn ti nwọn si ba wọn ro 'jọ ni "KOTU" pe nwọn nkakiri Ilu lai ni ọkọ: o geregere ni a gba lọwọ awọn t' o jẹbi ẹsun yi, iwa na si buku: ṣugbọn nisisiyi, a wo pe pipele l' npele si i. A ṣe awọn ALAṢẸ iṣẹ titun yi ni iranti ọrọ yi, ki nwọn ba le san ṣokoto giri, fun yiyọri iṣẹ na si rere gbogbo enia. A si tun sọ nipa ti owo ti a nfẹ, ti a si sọpe ki Ilu bẹrẹ si lati da gẹgẹbi BALE ILU (Ọgbẹni HENRY CARR) ti sọ pe iṣẹ awa ara ilu ni, ko kan Ijọba gbogbo wa l' a mọ pe ode le l' akoko yi, ṣugbọn sibẹsibẹ a ni ireti pe awọn enia yio fi tifẹ-tifẹ tọwọ bọ apo wọn fun iṣẹ IGBA-EMI-LA yi, a si damọran pe lẹhin igbati Ilu ba sa ipa wọn tan nipa didawo l' ona bayi, o yẹ ki AJO IGBIMO NLA t' o di iṣẹ yi mu ke si IJOBA lati ṣe iranlọwọ diẹ fun wa nipa fifi owo kun u, ti eyi ti a ba da ko ba to.

Ki Alafia ati Ilera ti a nfẹ nipa dida iṣẹ yi silẹ lãrin wa l' ọdun ni, ma sai tẹ olukuluku wa lọwọ, AKA-LILE NI IPEKUN Ọrọ.

---

**XMAS! XMAS!! XMAS!!!**

Place your Orders for your Private Christmas & New Years Greeting Cards in time.

SAMPLE BOOK containing various Styles will be seen at 35 BREADFRUIT STREET, Lagos.

**Very Cheap.**

## KILOPO? I.

LATI ỌWỌ, *EDITOR* EKO AKETE.
[ A ko gbọdọ da Iwe yi tẹ, lai gb' aṣẹ.]

### ỌRỌ IṢAJU.

Kilọkilọ ni mo fi iwe yi ṣe fun ẹnikẹni ti ko ni ti ra, ko to mo fẹ rin, nipa ifi ikanju ṣe ohun ọpọlọpọ ṣaju agbara wa lati ṣe wọn.

Adura mi ni pe ki iwe yi le ṣe olukuluku ẹniti o muka ni rere. *Amin.*

### IBOSI OWO!

Ninu ọpọlọpọ nkan ti awa enia nsare si lati ni, aiye yi ni owo ; ọna pupọ lo si wa, ti a fi nle pa e : ko dede ti eyi fi nri bẹ, nigbati o jẹ pe owo ṣe agbara kan : a si mọ pe "owo ko si enia ko sian : owo kosi obirin ko pe ọkọ l'esiki, " ibosi owo ! ! Ṣugbọn ninu isare bayi, anu ṣe ni pe ọpọlọpọ lo ti sa asa fi ogun igi : opo na si pọ rekoja ala, fun awọn ẹlomiran ki owọ wọn to le tẹ "eku ida ki wọn to bere iku to pa baba :" ninu ire sisa yi : ẹlomiran nku sọna : ẹlomiran ti di ero ẹwọn ! nipa bayi nwọn ki si le to ẹgbẹ ati ogba wọn mọ : ṣugbọn ju gbogbo rẹ lọ, fi elomiran ba si le nkan yi ba, yala nipa ṣiṣubu s' owo ni o, tabi nipa ogun jijẹ, tabi nipa ọna miran, o di pe kọ ṣiju si inakuna, ki o si matẹ ifẹkufẹ : asẹhin wa asẹhinbọ, owo yi akan iyẹ mọ apa, a si fo lọ ; o di pe ki oluwarẹ tun bẹrẹ si ṣe wahala : eyi fẹrẹ ba owe wa yi mu ti o wipe ; "Owo akoni ọmọde, akara ni yi o fi ra jẹ," o si ṣoro fun irufẹ ẹni bayi ki o to le ni itẹlọrun. Bi oni owo ọran, bi o ko ni, ọran :—Kilopo ?

### AWUN!

Iṣe kekere kọ lo wa ki a to le tu owo jọ : oriṣiriṣi ọna ẹwẹ lo si wa, ki irufẹ eyi ko to ti bẹ : ọna ti o si wọpọ larin awọn, ẹlomiran ni ki nwọn ma fi ebi pa ara wọn : nipa ọna bayi ni ọpọlọpọ ti fi di igi owo, o si ṣoro ki a to mọ pe owo ngbin ninu ile wọn ; ijade wọn ki si wu ni lori : nipa ọna bayi ni a fi nri aroro ati awuniwuni enia ti wọn ki nbikita lati fa awọn ẹbi wọn mọra : ile wọn a si da bi aginju : bi nwọn ni ọgọrun owo papa (£100) o di ki nwọn ma sare igba (£200) bi nwọn si ni igba kẹ, o di ki nwọn ma sare ẹgbẹrun (£1000;) opo pupọ ni eyi ati aibalẹ ọkan, bayi ni nwọn yi o si ma ba ọna yi lọ bi ẹnipe awọn lo gbe aje lulẹ ti o fi yọ ike ! ninu irufe ọna bayi, boya lojiji aisan nla kan a kọlu wọn, ti yi o si ma nru wọn na owo yi bi omi : bẹni aisan ni njẹ oriki "Fi mi pamọ ki npa ọ" bi nwọn si nfa tikọ lati na owo na ni irufẹ iẹba bayi, bi nwọn ba ṣeṣi "ṣe wo" owo a di ti aja, a di ti ẹran. A Kilopo ?.

### AYA BẸRẸ OṢI BẸRẸ.

A le wipe opo tabi ikanju ati ni aya lọ tẹle opo ati lowo, a si ri ọpọlọpọ ninu awọn ọdọ wa l'ọkunrin l'obinrin ti o jẹ pe ko si ero meji ti o wa ninu wọn ju ati gun oke agba yi lọ, ilobinrin pupọ jẹ ẹwun awọn miran, ko si si ohun ti on tete ta ni loṣi to eyi fun ẹniti ko to pẹmu rẹ gbe : nitoripe bi aya ba ṣẹ di mẹta tabi mẹrin lọdọ elomiran, opo ọpọlọpọ ni : bi Mary ṣeṣi kofiri pe o nlo ifẹ ju si Sally, o di gbọn-mi-si-omi koto : bi o si fẹ 'hin ju si ABẸKẸ, lọgan AṢABI a gbija : nitotọ "opo ni 'ṣa, opo ni ni yọ" melo ni a o la ninu ogọ iyọ, ki ẹnu ta ni ? A ko ni aya fifẹ ju ikan lọ jẹ ewọ : ṣugbọn ọpọlọpọ ọkunrin lo wa ti wọn ko ni ti to ila 'de, ti nwọn de, ti o si nru mọ wọn loju " ohun ti o mu eyi wa ni ikanju awa ọkunrin lati tete ni obinrin : nigbati a ba ranti pe "owo l' obinrin mọ," ibaunjẹ pupọ ni fun irufẹ awọn onikanju bayi nigbati inawo irufẹ ọna yi ba nbẹrẹ si ta wọn lori : opin rẹ ni ṣe olukuluku aya a si di ti ẹlomiran iwọ pada a si wa so agbẹjẹ mọ di pẹlu ironu pe ohun ti ọwọ rẹ koiti to, o lọ fi gọgọ la : ni igbagbe pe "owo lo wọn iyawo ko wọ :" gbogbo fuja rẹ ijọ kin a si di asan : ni kẹhin, ẹniti ko mọ igbati ojo rọ, a si wa lọ ṣọ :—Kilopo ?

### OLOWO L' AIYE MỌ!!

Bi o ti jẹpe kiṣe ohun to buru lati ni owo, sibẹ ọpọlọpọ lowa ti nwon ki nbikita ati gba ọna ẹburu lati ni : ṣugbọn a mọ daju pe ọna ti owo ba gba wa ni yi o gba lọ, eyini ni pe, igbakugba ko ni owo ti a ko ba lagun rẹ nbani k' alẹ.

Ẹlomiran a tilẹ "ri ẹṣẹ aṣiwere bu ṣogun" nigbati, "ọlọgbọn ko jẹ mu ti rẹ wa :" eyi kisi ṣoro lati mọ nitori irufẹ enia bayi ti o ri "apa bana" ko le ṣe ko ma lo owo na ni ilo 'omi ojo :" nigbati o baṣe gbẹdẹ tun irufẹ awọn ẹni bayi ni a ma nri ọpọlọpọ enia ti nwọn a ma bẹrẹ si wipe a nlọ sọdọ *cousin* ! boya ti aba wadi rẹ, a kole ki irufẹ awọn ẹni bayi ki *cousin* ọsangangan yi! ṣugbọn jẹki 'o fẹsi ' irufẹ enia bẹ tabi ki ṣa ṣi, nigbana ni iwo yi o mọ gbo irufẹ ede bayi pe, ta lo mọ ẹiyẹ to ṣu o !!!

Nitotọ, owe wa kan feyi han gbangban pe "Oṣi ni njẹ ta ni mọ ọ. Owo ni njẹ mo ba ọ tan ! ! !— Kilopo ?

### ALUGBAGBA. (*COBBLER.*)

Nigbalailai, awọn ọga iṣẹ, larin wa, jẹ awọn olokiki enia, nitori ogbọn-ori wọn ti wọn nlo fun oriṣiriṣi iṣẹ ti wọn ba nṣe, ibaṣe iṣẹ gbẹna-gbẹna, *carpenter*, a r a n ṣ ọ, *tailor* ọmọ 'le *brick-layer* alagbẹdẹ-wura, *gold-smith*, tabi awọn iṣẹ miran. A ripe ọpọlọpọ ọdun ni awọn enia wọnyi tilo gẹgẹ bi ọmọ-iṣẹ, labẹ ọga wọn tobẹ tojẹpe a ko le fi ọwọ rọ wọn sẹhin ninu iṣẹ wọn gbogbo : Ṣugbọn mo bere, bawo ni awọn ọmọ wa ti nkọ iṣẹ wọn si

nisisiyi ? Ẹlomiran tilẹ nlọ ṣe iwe Adehun, *Ageeement*, pe on kofẹ gba ju oṣu mẹfa lọ lati kọ 'ṣẹ (bi iṣẹ alagbẹdẹ-wura) lọdọ ọga on !!! Bẹgẹgẹ si ni iṣẹ aranbata pẹlu; ogo ni a npe irufẹ awọn ẹni bayi ni alugbagba !! nitori ikanju wọn lati di ọga fun ara wọn, lai jẹpe oyi iṣẹ na ti da loju wọn? Bi ẹniti o ba jẹ alugbagba bayi ba ranṣọ fun ọ, yi o dabi "agbawọ-ẹwu, bi ko fun ọ lẹsẹ; a ṣo ọ!" a tile nri awọn ẹlomiran ti wọn nfi OṢU MẸTA kọ iṣẹ *gold smith* ti wọn si sọpe wọn ti ja fafa ninu iṣẹ na? ikanju ati malọ ṣiṣẹ fun ara ẹni lo nṣe ọpọlọpọ leṣe yi: bi irufẹ awọn ẹni bayi baṣe orukọ wura fun ọ, idamẹta orukọ na yi o jẹ idarọ, yi o si dudu-họhọ: ẹ tilẹ wo iṣẹ arẹrun, *barber* a nri awọn ti nwọn ni nwọn ti kọ iṣẹ ni tan lọ lọ ọga wọn ni iwọn OSẸ MẸFA !!! ẹ jẹ ki a mọ pe asẹhinwa-asẹhinbọ, Alugbagba enia npa ara rẹ lokuta ni,—Kilopo ?

---

## ANFANI TO WA NINU EDE ILẸ WA.

### ẸBUN EKEJI. [ *SECOND PRIZE* ]

Ede ni pataki jẹ ohun ti a le fi fi ino inu ẹni han, olukuluku ni o si ni ede tirẹ.

Anfani pataki ti ari ni wipe, ede olukuluku rọrun fun ju gbogbo ede ti o ku ti o le gbọ lọ, gẹgẹ bi owe ilẹ yoruba ti o wipe:—Oju oloju kole jọ oju ẹni Hausa, ni ede tirẹ, Tapa ni ede tirẹ, Yoruba si ni ede tirẹ pẹlu ati ọpọlọpọ ilu miran ni ilẹ enia dudu, funfun, ati pupa, gbogbo ilu ti o ni ede wọnyi ni wọn jẹ anfani ede ti won, bi o tile jẹ wipe ko rọrun leti lati gbọ. Mo gba ọdun melo ni ilẹ ajeji, bi ati wipe mo gbọ ede wọn to, ṣugbọn iko ni irọrun lati sọ ati lati daṣa sinu rẹ gẹgẹ bi awọn ti a bi ninu rẹ, eyi mu ki a mọ sibẹsibẹ wipe ajeji ni mo sa jẹ.

Ede ẹni dara fun ni, o si rọrun fun ni lati kọ ju ede ti o ku lọ, nitoripe a ri wipe o yẹ wa ni a ṣe da mọ wa lati ọwọ Ẹlẹda wa ti o mọ rere ati buburu.

Ẹni ti abi ni odi, kole gbọ ede kan, o si ṣoro bi o ti wu ki iya jẹ to, kole lanu rẹ lati wipe a jẹ on ni iya, ko si le la idi ara rẹ, anfani kan si tun ni eyi sa jẹ.

O dara lati kọ ede ajeji nitoto, nipa ọgbọn ti a o ri ninu wọn, ṣugbọn ede ti a bi wa bi ni eyi ti o leke, nitori a ko dagba kọ, o si jẹ ajẹbi ati ajo un ba, on si ni yi o ma wa fun iran ti nbọ ti ki yi o jẹ ki oriki ati orukọ ilu wa ko parẹ.

Aṣa ni ohun keji ti o tẹle ede, gẹgẹ bi ede ilu bati lọ, bẹni aṣa rẹ yio ri. Ajeji ko ni dabi onilẹ bi o tilẹ gbọ ede, ko ni ko ri akoja laisi aṣa rẹ ninu rẹ.

Ni akoja mo gbadun ede ilu ti a bi mi ju eyikeyi ninu ede ti mo gbọ lọ nitori o ntẹmilọrun ati ninu ohun gbogbo ti mo ba sọ fun awọn enia mi ni wọn ngbọ lagbọye jinlẹ.

E. ADE: MACAULAY,

36, Moloney Street,
Ebute Mẹta.

## PREACHERS FOR TO-MORROW

### AWỌN ONIWASU OLA.

### ROMAN CATHOLIC.

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi.

| (Morning.) | Masses Isin Arọ. |
|---|---|
| 6.30—7.30 | 8.30—8.30 |
| 7.30—8.30 | 93.0—10.30. |

| (Evening.) Masses (Benediction) | Isin Ibọ |
|---|---|
| 4.45—5.30 | 6.45—7.30. |

Time. ANGLICAN. Preacher.

9 a.m.—Christ Church Rt. Rev. Rt. Bishop of Lagos
9 a.m. & 6.30 p.m.—St. Paul's (Breadfruit) Ven Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi
9. a.m.—St. John's (Arọlọya) Rev H. V. E. Johnson
6.30 p.m. do do.
9 a.m. 4 p.m.—St. Peter's (Alapako) Rev J. A. C...
9 a.m. & 6.30 p.m.—Holy Trinity (Ebute Ero) Rev S. J. Gonsallo
9 a.m.—St. David's (Jordan) Rev J. A. Leigh

### WESLEYAN.

10.30 a.m.—Tinubu Rev J. C. Cole
7 p.m. Rev. A. N. Cole
10.30 a.m.—Ereko Rev. S. A. Pearse
7 p.m. " E. K. Ajai-Ajagbe
10.30 a.m.—Olowogbowo Rev. D. A. Beckley
7 p.m. " J. C. Cole
10.30 a.m.—Ọbun Eko Rev E. E. Williams
7 p.m. Rev. D. A. Beckley

### AFRICAN (COMMUNION)

9 a.m.—Jehovah Shalom Bro J. T. A. White
7 p.m Bro. Ignatius Martins
9 a.m.—Erelu Rev. J. F. Ogunko
4 p.m. Bro. J. H Lawson
9 a.m.—Bethel Rev Supt J. A. Lakẹru
(21st Anniversary of the Establishment) Special Sermons
6.30 p.m. Rev. Supt. S. A. Coker
10.30 a.m.—African Methodist Bro. E. A. W'ms
4.30 p.m Bro. E. A. Amosu
9 a.m.—Araromi Church Rev. E. C. Alabi
4 p.m. Bro. Joseph Bandele

### EBENEZER.

9 a.m. Rev. Bro E. Alao Ojo
6.30 p.m. Bro. M. D. Adegboye

### ST. STEPHET'S (ẸPẸTẸDO)

9. a.m & 4 p.m, Very Rev. J. G. Campbell

### BROTHERHOOD.

7.30 a.m—Ilupesi Bro. Arinọla Ibaru
7 p.m. " Pastor A. Adedeji Iṣọla

### AHMADIA.

5.30 p.m.—Open Air Service Prof. A. R. Nayyar (Vincent Street.)

### COLONIAL CHURCH. (ỌDAN)

A nyan Awọn Alufa si Ile Isin yi lọsọsẹ.

## DR. RANDLE NI ILU OYINBO.

Gẹgẹ bi gbogbo wa ti mọ, Ọgbẹni Onişegun yi lọ si ilu Oyinbo laipẹ yi, o wa şe alabapade ẹniti o jẹ Oju Oyinbo Oniwe Irohin "*West Africa*," iyẹn si bi i lere abere ẹhin, on na si sọ diẹ ninu ọrọ ti Eko, ata ọrọ ti o sọ l' a tumọ si ede Yoruba fun kika ati fifi si ero awọn ara wa ti ko mọ ede Oyinbo lati ka.

IYONU AWON IMALE:—Ni ero temi, iyọnu yi, ti isin kọ, bikoşe ọrọ ilu, yio si dara ki gbogbo wa tete mọ eyi, ki Ijọba si mu ọrọ na ni kan-nkanşi lati fi alafia si ilu, awọn Imàle ti o nyọnu yi jẹ awọn ti o yẹ ki a fi ọwọ agbara mu lati dabobo nwọn nitori ti ara wọn. Ni *March* ti o kọja, awọn Oniyọnu wọnyi tọ Ijọba lọ lati sọ pe ija ojojumọ yi su nwọn, nwọn fẹ alafia, bi a ba si ti sọ ọ si ni nwọn o gba. Ijọba dahun pe o dun mọ wọn lati gbọ bẹ, nwọn si ni lati gba pe nwọn.o wa bi nwọn ti wa ri. Nwọn j' ọhẹn. Emi, gẹgẹ bi Baba Egbẹ, "*People's Union*" ba ilu yọ nigbana fun alafia ti o tun pada. Ọjọ diẹ lẹhin eyi, ikan ninu wọn sọ fun mi pe arekereke ni alafia ti awọn sọ pe awọn fẹ, eredi rẹ ni pe ninu awọn nfẹ ki gbogbo Imale papọ, nitori ati mu Eleko pada si ipo rẹ. Nitotọ, ko si otọ ninu iwa wọn. Nwọn pa ọrọ wọn mọ fun ọsẹ meji tabi mẹta, lẹhinna ija miran tun bẹ. Ninu ọkọ ti o kọja, mo gbọ pe nwọn lọ si Mọşalaşi nla l' Eko nibiti iyọnu tun wa ti a si lu ẹlomiran. Lasingbo l' arin awọn enia yio ma wa titi Ijọba yio fi fi ọwọ agbara mu alafia si arin wọn.

ỌRỌ TI ELEKO:—A bi Dr. RANDLE pe ewo l' o ri sọ si ede aiyede ti o wa l' arin Eleko ati Ijọba *Nigeria*, eyiti o mu pe ki Gomina fi sọ pe a ko ni ka si mọ, ti o si da owo rẹ duro?

Dr. RANDLE ni on ko gba pe eyi jẹ ede-aiyede lasan l' arin Eleko ati Ijọba. Ede-aiyede pataki ni l' arin Eleko ati iye awọn l' Eko ti a ka si aşoju l' arin ilu.

Iye awa ti mo nsọrọ rẹ yi ko ri si ọrọ ti ẹ nsọ sinu "*West Africa*" nipa ohun ti o şelẹ wọnyi. A ko ti fẹ sọrọ gbangba sinu Iwe-Irohin titi di isisiyi nitori a mọ ero iwe na ni kikọ iwe bi o ti şe, eyini ni ero iwa ẹtọ si ẹnikẹni ninu aşaju enia dudu. Ohun ti mo ni ero pe Iwe-Irohin na ko mọ tabi ko fi siwaju ni otọ yi pe şaju ki awọn ẹlẹjọ to de si ilu yi, nipa ti ẹjọ ti a mu wa si "*Privy Council*," nipa ilẹ Apapa ni aiyede yi wa nipa ti ẹniti o wa n' ipo olori ile Dosunmu.

Ki a pada sẹhin si iwe adehun ti a fi fi Eko tọrẹ, ki o le ye ni, mo le sọ pe eşi ni ti a ba sọ pe adehun na dọgba. Ko ri bẹ rara. Işegun ti ko si itajesilẹ ni, ẹniti o şegun si ni lati sọ ohun ti o fẹ. Boya yio ran awọn ti ko mọ lọwọ bi mo ba sọ pe a le ri eredi iwe adehun na ni irohin ti aşayan Igbimọ lori *Africa, June, 1865, Appendix Page 357.*

O sọ bayi. DOCEMO—LAGOS. "Ni *1855*, Akitoye w' aja, Dosunmu ọmọ rẹ si gori oye, ẹniti ọgbọn rẹ ko pọ, ko si pẹ ki o to han pe ko to ipo oye rẹ gbe. Laisi Olori ti o ni aşẹ to lati tẹ onirunru awọn oniyọnu ti o ngbe Eko ni gába. Ọpọlọpọ iyọnu l' o nwa. Ko si idabobo ti o to fun ohun ini, ko si ọna ti a fi le gba igbese. Nşe l' a nko awọn Onişowo jẹ, a ko si le ri idajọ ododo gba afi bi a ba fun awọn ti o sunmọ Ọba ni owo ẹhin. A nfi enia şẹbọ nibiti ko jinna si ilu, a si sọ pe a nmu ẹru wa lati agbegbe rẹ; aşẹ Dosunmu lori awọn enia rẹ jẹ t' ẹnu lasan."

DOCTOR RANDLE wa nba ọrọ rẹ lọ. Bi eyi ba ri bẹ, mo ro pe iwe adehun yi dara pupọ, eyi f' ara han ni ti Ijọba dada ti o wa nisisiyi. Eleko jẹ ọmọ Baba rẹ, iwa ti a ko gba ni *1865*, a ko le gba a l' oni.

Ni *1920*, Igbakeji Gomina BOYLE, da Eleko duro, ẹniti o mọ otọ ati itan Ọkunrin yi. A mu ọrọ yi si iwaju SIR HUGH CLIFFORD ẹniti o şeşẹ gba aşẹ Ijọba. Lẹhin ti o ti ro o dada,

SIR HUGH CLIFFORD pe awọn şaşa ti o nşe ilu lati wa ba on jiroro nipa rẹ. Gbogbo wọn l' o f' ohun şọkan pe eyiti BOYLE şe dara, afi awọn meji. Nwọn si ladi bi o ti şe dara. Awọn meji t' o ku sọ pe o yẹ ki a fun Eleko l' aye si nitoripe ko mọ. Nikẹhin Gomina CLIFFORD ni ti awọn ti o pọ ni on yio şe. Nigbati nwọn ti kuro nibẹ tan, ẹgbẹgbẹrun enia l' o lọ ba Gomina CLIFFORD, nwọn si ni ko ma gbọ ti awọn ti o pọ, nwọn ko ri nkan sọ lati fi gbe ọrọ wọn. SIR HUGH CLIFFORD gbọ ẹbẹ wọn. O ba Eleko wi, o si gbe si ipo rẹ.

Igbẹhin rẹ ni pe awọn ọlọtẹ nrẹ Ijọba jẹ. A fun Eleko ni Ajẹlẹ, Igbimọ Ilu ati Igbakeji Ọba, gẹgẹ bi olubadamọran, sibẹsibẹ, nigbati o gbe Ọpa rẹ fun Oloye OLUWA, ẹniti o mbọ wa si Ilu Oyinbo nipa ẹjọ rẹ, ko wa amọran wọn ninu nkan ribiribi yi. Nigbati a gbe Ọpa yi de Ilu Oyinbo, Ọgbẹni HERBERT MACAULAY ngbe kiri ni gbangba, o si nwasu fun awọn ara Ilu Oyinbo nipa ti iwe adehun ti a fi ilẹ tọrẹ. Eyi si bọ si akoko ti awọn German nsọ pe iwa arekereke ni ori ẹ ede Gẹsi fi ngba ilu.

SIR HUGH CLIFFORD sọ fun Eleko pe ki o yọ ara rẹ kuro ninu ohun ti Ọgbẹni HERBERT MACAULAY nsọ, Eleko kọ. SIR HUGH CLIFFORD bẹ ẹ ni 'kọkọ ati nigbangba pe ki o şe bẹ. Şugbọn o kọ jalẹ SIR HUGH CLIFFORD si ro pe işẹ on ni lati yọ ọ loye.

Awọn Ẹbi Dosunmu ko fẹ nkan ti Ijọba şe yi. Nwọn sọ pe bi a ba ti fi ẹnikan jọba, afi iku lo' le yọ ọ loye. Nipa eyi, nwọn ko ba Ijọba şe akitiyan. A fi han wọn iru ohun ti nwọn şe, eyi jẹ iyaju si Ijọba ati pe o lemu iya ti nwọn ko ro wa.

Ọgbẹni Onişegun yi sọ awọn ọrọ miran. Şugbọn eyiti o kan wa pupọ ni a gbidanwo lati şe itumọ rẹ yi. Gẹgẹ bi ọrọ Onişegun, a ri gbangba pe ede-aiyede yi ki şe l, arin Eleko ati Ijọba, şugbọn l' arin Eleko ati awọn Ẹgbẹ Onişegun yi. Ijọba ni gbogbo wa ti mọ ri, şugbọn Ọgbẹni wa yi ni ki işe bẹ. Eyi mu wa ş' abere pe—Awọn wọnyi ha ni Ijọba eyiti Gomina wa nşe oju rẹ.?"

FANOKUN.

---

## IJỌ ENIA DUDU.

Ijọ ti Eko (*Bethel*) yio şe iranti ọdun kọkandilogun ti ijọ Enia Dudu ti fẹsẹmulẹ nipa awọn ipade wọnyi :—

*Friday, 13th October, 9.30 a.m.* Ipade awọn Ọmọde. Ọgbẹni B. Owenson Joseph ni yio joko lori aga. Awọn ti yio si sọrọ ni Ọgbẹni E. A. Thomas ati E. A. Oni.

*7 p.m.* Adura Alẹ. Alufa alabojuto Agba yio şe Iwasu pataki ninu eyiti yio tan itan idasilẹ Ijọ wo.

*Sunday, 15th October, 9 a.m.* Isin idupẹ labẹ Iwasu pataki Alufa alabojuto J. A. Lakẹru ti Ijọ Salem.

*7 p.m.* Isin pataki ni ede Gẹsi, Alufa alabojuto S. A. Coker ni yio şe Iwasu.

*Monday 16th October, 7.30 p.m.* A o şe *Magic Lantern.*

T'ỌRẸ T'OJULUMỌ NI A PE.

---

## AWỌN OLUKỌNI OBINRIN.

(*SCHOOL-MISTRESSES.*)

O jẹ aşa fun awọn olukọni obinrin lati ma ran awọn ọmọ ọdọ wọn nişẹ (awọn ti wọn nkọ ni ẹkọ) lọsi ọdọ awọn ọkunrin ti wọn ba fe fi iwe (*letter*) şọwọ si i Eyi jẹ ohun ti ko dara lati ma ran awọn ọmọ kekere ni işẹ ni akoko igbati nwọn wa kọ ẹkọ ti wọn.

Oto ọsẹ marun nisisiyi ti Ojişe Ọlọrun Archdeacon OGUNBIYI fi oro yi şe iwasu ni ile Ọlorun ti *St. Paul Breadfruit* pe gbogbo awọn olukọni obinrin ko ni ife işẹ nwọn lọkan tọ bẹ mọ bikoşe ki wọn ma kọ iwe si awọn ọdọmọkunrin.

Ẹjọ oto asiko to yẹ ki tọkunrin tobinrin mura lati kọ iwe daradara ; Ẹ jọ ẹnyin oluko, ẹkọ gbogbo awọn ọmọ kekere lati fi ori si iwe wọn, ki nwọn ma ti kekere gbe ti okunrin dani, ati ki awọn ọkunrin ma si ti kekere gbe ti obinrin da ni.

Ẹ nyin olukọni, ẹniti iwe mi yi ba ba wi ki o lọ dawọ iru iwabẹ duro, ki o si ye şe.

ALAWO.

## Ẹ ṢU RIGIDI BO MI O!

OWO IRANLOWO TI A ṢI RI GBA NI WỌNYI.

| | | £ | s | d. |
|---|---|---|---|---|
| | Owo ti a ti ri gba | 7 | 5 | 0 |
| Ọgbẹni | J. Mosalewa Thomas | 0 | 5 | 0 |
| ,, | Karimu Kotun .. | 0 | 5 | 0 |
| ,, | A. B. Bernadine | 0 | 1 | 0 |
| | Aropọ | £7 | 16 | 0 |

Ara ilu, Ẹ jare Ẹ ma jẹ ko rẹ nyin,

A o ma jihin yi lọsọsẹ,

[ED.—E. A.]

## THE "AJENIFUJA" SEWING MACHINES.

These Machines are German Manufactured. Constructed of the best materials and skilful workmanship, very splendid in appearance, quick action and noiseless. No confusion, simple to thread, easy to operate. Durability Guaranteed will last almost life time, call for one at ORI-ADE STORE 97 & 109, Broad Street Lagos, Needles, Shuttles, etc., etc. in stock. Prices on application.

VIDAL R. COLE,

*Sole Agent.*

## "OṢEWỌNI!" (FAIR WARNING)

Ọgbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Aṣẹ lọdọ Ijọba *Nigeria*, nta orişirişi ọja ni Gbanjo, nile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ọjọ ọja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan arọ, lọsọsẹ. O ntete san owo ọja fun enia. Mu ọja rẹ lọ si bẹ.

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay.

(*Macaulay's Household Dispensary.*)

A nta orişirişi ogun Ilera ni Ile-ọja yi, to wa ni popo-nla (*Broad Street,*) l' Eko ni owo pọ ọ.

Awọn Ogun bi Oku, Painkiller, Ogun Inarun, Ogun Lakuregbe, Ogun Kuruna, Ogun Aran to dara Ogun Ẹda, Ogun Arẹmọ.

Ọgbẹni S. A. Q. Macaulay ẹniti oni Ile-Egbogi yi jẹ ẹniti o gba Aṣẹ ogun pipo (*Certificated Dispenser.*) lọwọ Ijọba Nigeria.

Ẹ LỌ DANWO: Ogun rẹ jẹ bi idan.

## ILE EGBOGI IṢẸ OLODUMARE.

A si ile Egbogi kan ti a npe ni Iṣẹ Olodumare si Ọja Ọbun Eko ni ile keta si Iga Oloye Aromirẹ. Nibẹ ni a le ri orişirişi iwosan fun oniruru aisan.

Ibaşe fun Orififo, Inurirun, Ẹda, Inarun, Aran Kinnişa, Ikọ, Ipa, Ọrẹrẹ, Ọṣẹ Egbogi, Egbogi Oju, ati awọn Oniruru ti a ko le to sihin tan

Rin de bẹ ki o wo o. Irohin ko to afojuba.

Iwọ ko tilẹ gbo oruko rẹ ndan?

Iṣẹ Olodunmare !!!

JOSHUA O. ADE: CRAIG,
*Alabojuto.*

## ILE OWO-ỌJA RIRANṢẸ TI AWỌN ẸGBẸ OYINBO C. F. HUTHCHINSON NI ILU OYINBO.

Ọgbẹni S. B. VINTURA, Aṣoju awọn Ẹgbẹ Oyinbo yi mura tan lati ranṣẹ awọn Ọja bi i *Herbadashery* eyini ni Ṣẹda, Onini, Owu-Ṣẹda alarabara, Ohun-Elo awọn Aranṣọ, ati oniruru Ọja bawọnni lati ọdọ awọn Oyinbo rẹ ni Ilu Oyinbo ni owo pọ ọ.

Ọgbẹni na si ni awọn Akẹtẹ *(Felt)* Bata Funfun ati awọn nkan miran daradara pẹlu ni tita ti owo wọn ko ta enia laiya.

Ẹ lọ danwo ni Ile-Owo rẹ ni Ita Tinubu, t'o kọjusi Kotu, l' Eko.

## ỌGBẸNI DURO: THOMAS.

ONIṢOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni orişirişi Ọja to de fun lati Ilu Germany fun tità: awọn nkan Awo Abọmafọ, Cement, Akara, ati Ọpọlọpọ Ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹkọwe si i, Number Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni 374: Number fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.

## Advertisements.

IPOLOWO ỌJA.

——:o:——

### ILE OWO IFẸ OLODUMARE.

Ọgbẹni Onişowo M. Bankọle Fadipẹ mura tan lati ranşẹ orişirişi Ọja fun ẹnikẹni lati ilu-oyinbo.

Ibaşe Ọja bi Ewe-taba, Ẹtu-ibọn, Awo, onjẹ-inipanu, Ẹrọ-ere ọmọde, Aşọ, ati awọn nkan bawọnni,

Enia le san Idamẹrin tabi Idameji owo silẹ gẹgẹbi iye-owo ọja rẹ ti to.

Awọn oyinbo rẹ ni ilu Germany şetan lati gba enia lawin ọja; nwọn yio si fi ọja ti o ju idameji iye owo ọja ti o ba fi ranşẹ si wọn, şọwọ si ọ, a o si fun ọ laye Oşu mẹta lati san owo toku. Maşini Ọlọwọ ati Ẹlẹsẹ daradara (Ọlọkọ rubutu ti Germany) nbẹ.

Ọgbẹni onişowo yi nfi Cocoa, Ekurọ, Epo ati orişirişi Awọ Ẹran şọwọ si Ilu Oyinbo fnn tita.

Ẹ lọ ba orire nyin pade lọdọ Ọgbẹni onişowo yi ni Ile-owo rẹ

Ebute Oluwa.
158, Marina L'Eko.

### LIQUOR LICENCES,

Notice is hereby given that all applications for Liquor Licences must be made to the Police Magistrate, Court House, Tinubu Square, on the prescribed forms not later than the 15th October, 1922 as provided under Section 28 of the Liquor Ordinance, 1917.

A. W. S. RUMENS,
*Secretary Licensing Board.*

Lagos, 28th September, 1922.

——o——

### READY.

**"Church and Politics."**
**(A Lecture)**

OR

THE DUTY OF THE CLERGY TO THE LAITY.

BY PROF: DENIGA.

SOLD at 24 Williams Street, Lagos.
3d. a copy.

AWON ẸGBE OYINBO ONISOWO TI A NPE NI

### E. H. STEIN ARA HAMBURG.

NEUERWALL 16 18. GERMANY.

Jẹ Awọn onişowo ti Ilẹ Enia Dudu, nwọn n nranşẹ Ọja fun ẹnikẹni to ba fẹ'ibaşe Ọja ti Ilu Ge[rmany] tabi ti awon Ilu oyinbo miran ta o wa lagbegbe *England* ati Germany.

Nwọn si nba enia ta Ọja bi Epo tabi Ekurọ ti a ba fi ranşẹ siwọn si Ilu awọn oyinbo (*Europe*) ni owo ti o jọ enia loju.

Kosi ewu kankan ni fi fi Ọja-kọja ranşẹ si wọn lati Eko tabi Ilu miran ni *Nigeria*.

Ki ẹnikẹni to ba fẹ ba awọn oyinbo yi şowo kọ tabi ki o kọwe si Aşoju wọn nibi Ọgbẹni Karimu Kọtun ti ita Ọba Dosunmu No 3, tabi ni ibi-işẹ rẹ (*Office*) ni Opopo-nla (*Broad Street.*) ati ni ibi-ifi Ọja pamọ si (*Forlo-nọvo Market Store*) L'Eko.

Ẹnikẹni le kowe ni ede Gẹsi, niti *German* tabi niti *French*.

Oruko adugbo awọn oyinbo onişowo yi ni ede *Wire* ni STEINAFRIK. Hamburg.

### GIDIGBO! GIDIGBO!! HEYA.!!!



Awọn RECORDS to nkọrin lede YORUBA pọ to wọbu ni ile owo.

MANN POOLE & COMPANY LTD.,
8 TINUBU SQUARE, LAGOS.

Ki la ti nş' oku l' ọrun?
Ki la ti nş' ori nile Iku?
Tutu tabi Gbigbẹ?
Ọpọkuyọku si ni, wa şa eyi to wu ọ ni—
8 TINUBU SQUARE, LAGOS.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.